# NÀÌJÍRÍÀ | NIGERIA

## USCIRF –FOR COUNTRIES OF PARTICULAR CONCERN (CPC)

Àjọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà lórí Òmìnira Ẹ̀sìn Lágbàáyé (USCIRF) jẹ́ àjọ èyítí ó dá dúró, tí kò ṣe òṣèlú tí ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí ó ń bójútó ẹ̀tọ́ sí òmìnira ẹ̀sìn tàbí ìgbàgbọ ní ilẹ̀ òkèèrè l'ágbàyé. Tí a ṣẹ̀dá nípa Òfin Àjọ Òmìnira Ẹ̀sìn Lágbàáye International Religious Freedom Act (IRFA)] ti ọdún 1998, USCIRF ń lo àwọn òṣùwọ̀n ti àgbáyé láti ṣe àbójútó àwọn ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn tàbí ìgbàgbọ ní ilẹ̀ òkèèrè tí wọ́n sì ń gba ààrẹ, akọ̀wé ìpínlẹ̀, àti Aṣòfin nímọ̀ràn. USCIRF jẹ́ àjọ tí ó dá dúró tí ó sì dáyàtọ̀ gedegbe sí Ilé-iṣẹ̀ Ilẹ̀-òkèèrèti orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ( U.S. Department of State). Ìjábọ̀ Ọlọ́dọọdún ti ọdún 2020 dúró fún àpapọ̀ iṣẹ́ tí ọdún kan láti ọwọ́ Àwọn alákòóso iṣẹ́ àti àwọn òṣìṣẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ láti ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ìwàkiwà tí ó wà nílẹ̀ àti láti dábàá òfin àwọn àmọ̀ràn èyítí ó dádúró fún ìjọba orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà. Ìjábọ̀ Ọlọ́dọọdún ti ọdún 2020 wà fún àkókò láti Oṣù kinni ọdùn 2019 títí dé Oṣù kejìlá ọdùn 2019, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ní àwọn ipò kan a ménuba àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó ṣe pàtàkì èyítí ó wáyé ṣááju tàbí lẹ̀yìn àkókò yìí. Fún àlàyé síwájú si nípa USCIRF, wo ààyè lórí ayélujára nibí, tàbí kí o kànsí USCIRF tààrà ní 202-523-3240.

## KÓKÓ ÌWÁDÌÍ

Àwọn ipò òmìnira ẹ̀sìn ní Nàìjíríà sì jẹ́ èyítí kò dára ní ọdún 2019, ní èyítí ìjọba- àtí àwọn ẹgbẹ́ l'áwùjọ ṣe okùnfa àwọn ìtàpásí. Ìjọba àpapọ̀ ń tẹ̀síwájú láti fi olórí ẹgbẹ́ Shi'a, Islamic Movement ní Nigeria (IMN) sí ìhámọ́, tí wọ́n si ń fi ìwà-ipá kọlu àwọn ọmọ ẹgbẹ́ rẹ̀ ní àwọn ìgbà ìwọ́ọ̀de àti ìfi-ẹ̀hónú hàn. Ní Oṣù kejè, ìjọba gbégilé ẹgbẹ́ náà, tí wọ́n ń sọ wípé wọ́n wu ìwà-ipá tí wọ́n si ń bí àwùjọ nínú. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN ń tẹ̀síwájú láti máa ṣe ìwọ́ọ̀de ní àfojúdi sí gbígbégilé náà, tí wọ́n ń sọ wípé àjọ àwọn kì í ṣe alájàgbila wípé àwọn kan ń lo òmìnira ẹ̀sìn, ìkórajọpọ̀, àti ọ̀rọ̀ sísọ àwọn ni. IMN ni ẹgbẹ́ Shi'a tí ó tóbi jùlọ ní Nàìjíríà, pẹ̀lú àwọn olùtẹ̀lé tí otó bíi milionu mẹ́ta. Láti ìgbà tí awọn ọmọ-ogun Nàìjíríà ní ọdún 2015 ti pa àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN tí ó ju 340 lọ ní ìpakúpa, kò sí òṣìṣẹ́ olóógun kankan tí a fi jófin nígbangba fún èyí.

Ní gbogbo ọdún náà, orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ti pe Àwọn àjọ Adàlúrú Ilẹ̀-òkèèrè Boko Haram Haram àti Ìpínlẹ̀ Islam ti Iraq àti Siria (ISIS)-Ìwọ̀ oòrùn Ilè Adúláwọ̀ ń tẹ̀síwájú pẹ̀lú àwọn ìfẹ̀míṣòfò wọn ní àríwá-ilà oòrùn Nàìjíríà àti agbègbè Lake Chad. Ní àárín ọ̀sẹ̀ Kérésìmesì, ISIS-Ìwọ̀ oòrùn Ilè Adúláwọ̀ gbé fídíò kan jáde tí ó ńṣe àfihàn ìpànìyàn àwọn ẹnìyàn mọ́kànlá (11) tí a mú ní ìgbèkùn ní ọ̀nà tí ó burú jáì tí wọ́n ńsọ wípé àwọn ńpa àwọn Kristiẹni ní ẹ̀san fún ikú olórí ISIS, Abu Bakr Al Baghdadi. Àwọn ẹgbẹ́ oníjàgídíjàgan náà ní àfojúsùn sí àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò ju ti èyíkéyì ọdún àtẹ̀yìnwá lọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé àwọn ẹ̀ṣọ́ ológun àti ara-ìlú gbìyànjú láti dẹ́kun àwọn ìkọlù kan, Boko Haram pẹ̀lú àṣeyọrí kọlu àwọn ipò ológun àti ọkọ̀ tí ó tò tẹ̀lé ara wọn kan, àwọn ilé, àwọn oko, àti mọ́ṣáláṣí; mú àwọn ará-ìlú, tí wọ́n sì pa àwọn tí wọ́n jígbé, tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn sì jẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọmọ-ènìyàn lọ́fẹ̀ẹ́. Láti ọdún 2009, Boko Haram ti lé kúrò ní ipò won àwọn ènìyàn tí ó ju milionu méjì lọ tí wọ́n si ti pa ẹgbẹẹgbẹ̀rún.

Àwọn ìṣòro nípa ààbò ti agbègbè sí agbègbè àti ìwà-ipá ajìjàgbara tàn káàkiri, jíjínigbé,wọ́pọ̀, tí ìwà-ọ̀daràn lápapọ̀ tún nípa tí kò dára lórí òmìnira ẹ̀sìn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìròyìn ni o wà nípa ọ̀ràn àwọn ìkọlù àwọn olórí ẹ̀sìn àti àwọn lọ́balọ́ba pẹ̀lú àwọn ilé ìjọ́sìn. Nínu ọgọgọ̀rún àwọn ìjínigbé tí ó lọ sókè ní ọdún 2019, àwọn oníròyín jábọ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìjínigbé fún owó ìdásílẹ̀ àti pípa àwọn àlùfáà Protestant àti Katọliki, àti pẹ̀lú ní àwọn ìpínlẹ̀ Enugu, Ondo, àti Kaduna . Jíjábọ̀ tí ó nííṣe pẹ̀lú ìkọlù ẹ̀sìn ní ìwà-ipá agbègbè sí agbègbè ní agbègbè Middle Belt dínkù sí ní àfiwé pẹ̀lú ọdún 2018; ṣùgbọ́n, àwọn ìjábọ̀ àwọn ìkọlù ìwà-ipá agbègbè sí agbègbè àti ìkọlù ajìjàgbara ẹlẹ́yàmẹyà ní gbogbo àwọn àwùjọ ṣìí ń tẹ̀síwájú, bíi ní Kaduna láàrín Kristiẹni Adara àti àwọn ẹgbẹ́ Musulumi Fulani , ní Zamfara, àti ní Taraba. Ìjọba Nàìjíríà kúnà láti mú ìdájọ́ òdodo àti ààbò gbérú ní ọ̀nà tí ó múnádóko fún àwọn ara-ìlú rẹ, tí kò sì ṣe àṣeyọrí láti kojú àìní tí ó pọ̀ fún gbígba ojúṣe àti ìbálàjà nípa àwọn aáwọ̀ àtijọ́.

## ÀWỌN ÌMỌ̀RÀN FÚN ÌJỌBA AMẸ́RÍKÀ

- Pe Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bíi "orílẹ̀-èdè tí a ní àìbàlẹ̀-ọkàn rípa rẹ̀, "tàbí CPC fún lílọ́wọ́sí tàbí fífi ara da ní tẹ̀le-n-tẹ̀lé ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn, èyí tí ó ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́, tí kò dára tí ó farahàn kedere, gẹ́gẹ́ bi a ṣe túmọ̀ rẹ̀ nípasẹ̀ Òfin Àjó Òmìnira nípa ẹ̀sìn (IRFA), àti láti tẹ̀síwájú láti pe Boko Haram gẹ́gẹ́ bíi "àjọ tí a ní àìbàlẹ̀-ọkàn rípa rẹ̀ "fún lílọ́wọ́sí ní tẹ̀le-ntẹ̀lé ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn, èyítí ó ńlọ lọ́wọ́lọ́wọ́, tí kò dára tí ó farahàn kedere, gẹ́gẹ́ bi a ṣe túmọ̀ rẹ̀ nípasẹ̀ IRFA:
- Wọnú àdéhùn kan tí ó l'ágbára, bí a ti ṣe fúnni ní àṣẹ lábẹ́ Ìpín 405 (c) ti IRFA, kí a sì pèsè àtìlẹyìn owó tí ó nííṣe àti ìmọ̀ràn, láti mú kí ìjọba Nàìjíríà gbé ìgbésẹ̀ pàtàkì láti kojú àwọn ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn, èyítí ó ní nínú ṣùgbọ́n tí kò pin sí:
  - Mú ìdánilẹ́kọọ fún àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba, awọn ológun àti ọlọpàá gbèrú lórí àwọn kíkojú ọ̀rọ̀ ìkórìraa tí ó dá lórí ẹ̀sìn; dídáhùn sí jàgídíjàgàn ẹlẹ́yàmẹyà; jíjábọ̀ àwọn ìwà-ipá tí ó wáyé lòdì sí àwọn ẹlẹ́sìn; tí a sì ńfi ìyà jẹ àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò tí a fi ẹ̀sùn kan wípé wọ́n lo ipá tí ó pọ̀jù àti ìpalára àwọn ẹ̀tọ́ ènìyàn miiran;

- Mu ki ètò àti ìwádìí yíyanjú aáwọ̀ pọ̀ si láti dín ìwà-ipá àti ẹlẹ́yàmẹyà tí ó dá lórí ẹ̀yà ẹ̀sìn kù;
- Mú gbígbé owó kalẹ̀ fún àtúnṣe ìpín ààbò àti ètò ìlànà tí ó bá òfin mu pọ̀ si, kí á sì jẹ́ kí àwọn olùkópa ilé-ẹ̀sìn lọ́wọ́ nínú ààbò àti àwọn ètò ìdájọ́ tó níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn rẹ̀; àti
- Fi àjọ ìwádìí kan tí ó dá dúró lọ́lẹ̀ [commission of inquiry (COI)] láti ṣe ìwádìí nípa ìdí tí àwọn akitiyan àwọn ẹ̀ṣọ́ aláàbò láti dáàbòbò àwọn agbègbè ẹlẹ́sìn tí a lè palára má múnádóko, àti pẹ̀lú àwọn Kristiẹni àti àwọn Musulumi, ní àwọn agbègbè àríwá àti àringbùngbùn orílẹ̀-èdè àti pàápàá fún pípa àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN ní ọdún 2018 àti ọdun 2019, kí a sì gbé èyíkéyì àwọn ìwádìí tí ó wúlò àti ẹ̀rí tí a mú láti inú àwọn àgbéjáde ọlọ́pàá síta; àti

- Ya owó sọ́tọ̀ fún àwọn ètò tí yóò kó ọmọ ẹgbẹ́ tí ó ńjà fún ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn, aláàbò, àti àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba jọ ní akitiyan ìlọ́wọ́sí láti dáàbòbò àwọn ibi-ìjọ́sìn àti àwọn ibi mímọ́ miiran.

## ÀWỌN IṢẸ́ & OHUN-ÈLÒ USCIRF TÍ Ó ṢE KÓKÓ

- **Ìjábọ̀ Àkànṣe:** Àarin gbùngbùn Nàìjíríà: Bíborí Ọ̀rọ̀ Tí ó léwu àti Ọ̀rọ̀ èsìn Tí ó ńfa Ìyapa Ní ibi kan
- **Ìjábọ̀ Àkànṣe:** Ọ̀fin Shari'ah ní Àríwá Nàìjíríà
- **Isé nípa Àwon tí a fi sí èwòn nítorí èsìn won gbígbàwọlé:** Leah Sharibu

## Àlàyé nípa ìrísí

Nàìjíríà jẹ́ orilẹ̀-èdè tí ó gbé ẹ̀sìn ga gan, nínú èyítí ẹ̀sìn ń kó ipa tí ó ṣe pàtàkì nínú ọ̀ṣèlú, ìṣèjọba, ààbò, àti ìdájọ́. Ìwé CIA World Factbook ṣírò iye ènìyàn rẹ tí ó pọ̀ju mílíọnu mẹ́tàléníġba (203 million) ènìyàn lọ, pẹ̀lú ìdá 53.5 nínú ọgọ́ọ̀rún tí a dámọ̀ bíi Mùsùlùmí, ìda 45.9 nínú ọgọ́ọ̀rún bíi Kristiẹni, àti ìda 0.6 nínú ọgọ́ọ̀rún tí wọ́n ń ṣe ẹ̀sìn miiran. Àwọn ẹgbẹ́ miiran ni àwọn tí kò gbàgbọ́ wípé Ọlọ́run wà, Baha'is, Júù, Hindu, àti àwọn tí ó gbà Buddha gbọ́. Àwọn ẹ̀sìn àtọwọ́dọ́wọ́ ti àbáláyé àti ṣíṣe ẹ̀sìn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ papọ̀ náà tún wà. Òfin orilẹ̀-èdè Nàìjíríà ti ọdún 1999 ńdáàbòbò òmìnira ẹsin tàbí ìgbàgbọ́, kò sì fi ààyè gba ṣíṣe ẹlẹ́sìnmẹsìn, tí kò dẹ̀ tẹnumọ́ ẹ̀sin kankan ní pàtó ti ijọba gbè lẹ́sẹ̀. Ìpínlẹ̀ méjìlá ti Mùsùlùmí pọ̀ gan ní àríwá ńlo òfin ọ̀daràn Shari'ah àti ìdílé ní ẹ̀gbẹ́ kannáà pẹ̀lú àwọn òfin alágbádá àti ti àṣà. Àwọn Òfin Ìfiyàjẹni Shari'ah kò fi ààyè gba ọ̀rọ̀ òdì, ti Òfiin ọ̀daràn Nàìjíríà náà tún ní nínú ẹ̀wọ̀n tí ó tó ọdún méjì fún bíbú ẹ̀sìn ẹlòmíràn. USCIRF ti jábọ̀ àdéhùn lórí òfin ọ̀daràn Shari'ah ní àríwá Nàìjíríà jíròrò àwọn èròngbà àwọn ènìyàn tí ó dá yàtọ̀ nípa àwọn àgbékalẹ̀ Shari'ah àti olọ́pàá *hisbah*, tí a sì ri wípé nína ènìyàn ṣì jẹ́ irú ìjìyà tí ó wọ́pọ̀. Ìjábọ̀ yìí àti àwọn miiran ṣe àfihàn ìwò tí kò tọ́ tí ó ńlọ ní àwùjọ àti àgbékalẹ̀ tí ó lòdì sí àwọn ẹ̀sìn kékékèé bíi Shi'a àti èèwọ̀ ní àwùjọ lòdì sí àìní ìgbàgbọ́ wípé Ọlọ́run wà àti ètò ẹ̀dá ènìyàn tí ó ńwo dídára àti ìṣepàtàkì ènìyàn ju nǹkan ti ẹ̀mí lọ.

Aáwọ̀ láàrín àgbègbè sí agbègbè ṣìí ńtẹ̀síwájú láti pa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìpínlẹ̀ lára, ní pàápàá àwọn àgbègbè ìgbèríko, tí ẹ̀yí sì níìṣe pẹ̀lú ìfigagbága lórí àwọn ohun-èlò ilẹ̀ àti omi, bí oko ṣe ńfẹ̀ si, bí ènìyàn ṣe ńpọ̀si, bí àwọn ohun ìjà ìléwọ́ ṣe ńtàn káàkiri, àwọn ìkùnsínú nípa ẹ̀sìn àti ìtàn, àti àwọn òfin jíjẹ́ ọmọ-onílùú. Gẹ́gẹ́ bí dídá ẹ̀yà àti ẹ̀sìn mọ̀ ṣe wọnú ara wọn pẹ́kípẹ́kí, nígbà miì aáwọ̀ láàrín àwọn ẹ̀yà ẹgbẹ́ méjì ní a lèpè ní aáwọ̀ àwọn ẹgbẹ́ ẹlẹ́ẹ̀sìn tàbí kí ó di gígbẹ̀san èyítí ó fa kíkọlu àwọn ènìyàn látàri ẹ̀sìn wọn. Ìdìbò ọdún 2019 kò mú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ aáwọ̀ ẹ̀sìn kan sí òmíràn dání. Ṣùgbọ́n, àwọn ìpolongo kan wá láti rọ àwọn olùdìbò ní pa lílo ẹ̀sìn, tí àwọn ìdìbò náà sì bàjẹ́ nípa àlàyé èké, ìrunilọ́kàn sókè láti wu ìwà-ipá, ríra ìbò, àti àwọn ìwà-ìbàjẹ́ miiran.

## Fífi agbára Tẹ Islamic Movement Mọ́lẹ̀

Ní ọdún 2019, ìjọba àpapọ̀ ti Nàìjíríà tẹ̀síwájú láti fi olórí IMN, Sheikh Ibrahim El Zakzaky, sí ìhámọ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ilé-ẹjọ́ kan ní ọdún 2016 ti pàṣẹ wípe kí a tú u sílẹ̀. Ní Oṣù keje, ìjọba gbégilé IMN, ṣùgbọ́n ẹgbẹ́ náà ń tẹ̀síwájú láti ṣètò àwọn ìpàdé ẹ̀sìn tí wọ́n si ń ṣe ìwọ́ọde yíká orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń pè fún títú Zakzaky sílẹ̀. Nítorí àwọn ìkọlù pẹ̀lú ọlọ́pàá ní Oṣù keje, IMN àti àwọn oníròyìn jábọ̀ wípé àwọn ènìyàn tí ó ju mẹ́sàn-án lọ ní a pa. Ní àkókò Awon ìwọ́ọde Ashura ètò ẹ̀sìn ní Oṣù kẹsan, IMN ti so wípé ọlọ́pàá Nàìjíríà ti pa àwọn olùtẹ̀lé tí ó ju méjìlá lọ. Ní Osù kejo, ìjọba gba Zakzaky àti ìyàwó rẹ̀ láàyè láti rín ìrìn-àjò lọ sí orílẹ̀-èdè India fún àbójútó ìṣègùn; ṣùgbọ́n, lógán tí òun dé ọ̀hún, Zakzaky kọ ìtọ́jú. Ní Oṣù kẹwàá, ó kéré tán ọmọ ẹgbẹ́ IMN méèsan ní a jábọ̀ wípé kò jẹ̀bi àwọn ẹ̀sùn nínú ẹ̀yí tí jíjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ IMN àti kíkórajọpọ̀ ní ọ̀nà tí kò bá òfin mu wà nínú rẹ; iye àwọn miiran tí a kò mọ̀ ṣì wà lẹ́wọ̀n. Ẹgbẹ́ náà tí ó gba imisi nípa dída ojú ìjọba Iraani bolẹ̀ ti ọdun 1979, tí wọ́n sì ńlo àwọn fọto ti Ayatollah Ruhollah Khomeini àti ti Ayatollah Ali Khamenei lórí ààyè ayélujára rẹ̀, ẹgbẹ́ náà ti wá di àfojúsùn ìkọlù fún ìjọba Nàìjíríà, èyítí ó ńlo ipá líle tí ó pọ̀jù láti fi agbára tẹ̀ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN àti àwọn ìṣe wọn mọ́lẹ̀.

## Boko Haram & ISIS-Iwọ̀ oòrùn Ilẹ̀ Adúláwọ̀

Ní ọdún 2019, Boko Haram àti ẹ̀ka ISIS ti Iwọ̀ oòrùn Ilẹ̀ Adúláwọ̀ ń tẹ̀síwájú láti ja ogun ífẹ̀mísọ̀fò tí wọ́n ńwá láti ṣẹ̀dá ìpínlẹ̀ islamu tí ó báramu pẹ̀lú òye èrò Salafi-jihadi wọn. Àwọn ni wọ́n ńṣe okùnfa àwọn ìkọlu lòdì sí àwọn ilé-ìjọ́sìn, àwọn ará-ìlú, àti àwọn àfojúsùn àwọn ológun. Ẹgbẹ́ náà tún kọlu àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Ekklesiyar

Yan'uwa a Nàìjíríà (EYN, Ìjọ Àwọn ará ní Nàìjíríà), tí wọ́n jí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ EYN gbé tí wọ́n bàjẹ́ ìjọ EYN kan ní Oṣu kẹta. Àwọn oníròyìn jàbọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí a furasí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Boko Haram fún kíkọlu àwọn mọ́ṣáláṣí ní Maiduguri, àti ní Oṣù Kejì àti Oṣù kẹfà. Ní Oṣù keje, àwọn alákatakítí Boko Haram kọlu ìsìnkú kan ní Ìpínlẹ̀ Bornu tí wọ́n sì pa ó kéré jù ènìyàn márùndínláàdọ́rin (65). Ọmọ ogun Nàìjíríà ní a fi ẹ̀sùn kan léraléra nípa ìwà-ìbàjẹ́ nípa àwọn ẹ̀tọ́ ènìyàn lòdì sí àwọn ènìyàn tí a ti ṣí nípò kúrò ní ilé wọn àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Boko Haram tẹ́lẹ̀ tàbí ti a fura sí—tí ó ní nínú ẹgbẹ̀ẹgbẹ̀rún àwọn omode. Ní àkókò kannáà, àwọn ọmọ ogun bẹ̀rẹ̀ àwọn akitiyan láti dẹ́kun ìwà-ipá tí ó ń pin ni l'ẹ́ẹ̀mi kí wọ́n sì mú àwọn àjọṣepọ̀ l'áwùjọ gbérù, bíi ṣíṣe àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kó ẹ̀sìn papọ̀ láti gbé lárugẹ ìrònú tí ó yàtọ̀ àti lílọ sí àwọn ìsìn àdúrà láti fi ọkàn àwọn olùjọ́sìn tí ó ń bẹ̀rù ìkọlù balẹ̀.

## Àwọn ìkọlù sí Àwọn ilé Ìjọ́sìn

Àwọn olùkópa jíjà fú ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn ńtẹ̀síwájú láti ṣe àwọn ètò láwùjọ láti mú gbèrú ìdáàbòbò àwọn ilé ìjọ́sìn àti àwọn ibi mímọ́ miiran, síbẹ̀ àwọn sì wà nínú ewu ìkọlù. Ní àfikún sí àwọn ìkọlù Boko Haram, ní ọdún 2019 àwọn ẹgbẹ́ àti àwọn onínúfùfù tí wọ́n ní nǹkan ogun tún kọlu àwọn ìjọ àti mọ́ṣíláṣí ní gbogbo orílẹ̀-èdè náà. Iní Oṣù kẹfà, àwọn òṣìṣẹ́ mú àwọn afurasí mẹ́ta fún gbígbìyànjú láti dáná sun Ìjọ Katoliki St. Augustine ní Kaduna. Ní Oṣù kẹsàn-án, ẹgbẹ́ àwọn ọ̀dọ́ Kristiẹni kan jábọ̀ kíkolu mọ́ṣíláṣí kan ní Ìpínlẹ̀ Delta láti inú ìbínú fún kíkọ́ ọ. Ní Oṣù kẹwa, a fi ẹ̀sùn kan ẹgbẹ́ búburú kan fún kíkolu mọ́ṣíláṣí kan tí wọ́n sì ṣe lára àwọn ọmọ ẹgbẹ́ rẹ̀ léṣe. Ní Ìpínlẹ̀ Anambra ní Oṣù kárùn-ún, àwọn oníròyìn jábọ̀ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Indigenous Peoples of Biafra (IPOB)—ẹgbẹ́ kan tí ó ń wá òmìnira—kọlu àwọn Kristiẹni márùn-ún, àti pẹ̀lú àlùfáà kan, fún ṣíṣe ìsìn ní àfojúdi sí àwọn àṣẹ ìgbélé IPOB.

## ÒFIN ORÍLẸ̀-ÈDÈ AMẸ́RÍKÀ TÍ Ó ṢE KÓKÓ

Ní Oṣù kẹjọ, Aṣojú orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà W. Stuart Symington fi ipò sílẹ̀, àti ní ọjọ́ kẹrin (4) Oṣù kẹwàá, Mary Beth Leonard ní a búra fún gẹ́gẹ́ bíi aṣojú orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà titun sí Orílẹ̀-èdè Olómìnira Nàìjíríà. Ní gbogbo ọdún náà, orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ṣe àtìlẹyìn fún àwọn iṣẹ́ ní Nàìjíríà tí ó ńkojú díndín aáwọ̀ kù tí ó sì ńmú ìdájọ́ àti ààbò gbèrú, èyítí ó ní nínú ṣíṣe agbátẹ̀rù ètò nípa Ilé-iṣẹ́ Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà fún Ìdàgbàsókè Láàgbáyé [U.S. Agency for International Development (USAID)] èyítí ó ńtẹjúmọ́ yíyanjú aáwọ̀ láàrín àwọn àgbẹ̀ àti darandaran. Àwọn oṣìṣẹ́ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà pẹ̀lú ìjọba Nàìjíríà àti àwọn ẹgbẹ́ tí wọ́n ńjà fú ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn lórí àwọn ohun tí ó níṣe pẹ̀lú òmìnira ẹ̀sìn. Ní ọjọ́ kejìdínlógún (18) Oṣù kejìlá, Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀ Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (U.S. Department of State) fún ìgbà àkọ́kọ́ fi Nàìjíríà sí Àkànṣe Àkójọ fún Ìwò (Special Watch List) fún àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n tí lọ́wọ́sí tàbí farada "àwọn ìtàpásí òmìnira ẹ̀sìn ní ọ̀nà tí ó burú jáì, "àti ní ẹ́kansi pe Boko Haram gẹ́gẹ́ bíi "àjọ kan tí ó fúnni ní àìbàlẹ̀-ọkàn, "gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe ní ọdún 2018. Ìrànlọ́wọ́ ìnáwó Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí ó pọ̀jù fún ọdún 2019 ní a yàsọ́tọ̀ fún dídáhùn sí pàjáwìrì àti ètò àbójútó ìlera, àti iye díẹ̀ fún àwọn akitiyan àláàfìà àti ààbò. Ní Oṣù karùn-ún, Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Aṣòfin fí àwọn àbá kan (H.Res.375/S.Res.170) lọ́lẹ̀ fún dídá ọdún karùn-ún tí Boko Haram ti jí ọgọ́gọ́rùn-ún àwọn ọmọ obìnrin láti Chibok gbé mọ̀ tí wọ́n sì ńpe Nàìjíríà láti mú àwọn akitiyan rẹ láti fi òpin sí aáwọ̀ náà àti láti ran àwọn tí a pa lára pọ̀si. Ní Oṣù kẹwàá, Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Aṣòfin fí àbá (H.Res.640) lọ́lẹ̀ tí wọ́n "ń dá ṣíṣe inúnibíni sí àwọn Kristiẹni ní ágbáyé lẹ́bi "tí wọ́n tọ́kasí àwọn ìkọlù àwọn Kristiẹni tí ó pọ̀ ní Nàìjíríà ní ọdun 2018 àti ọdún 2014.